# OKU ADELABU D'ORO O GB'ODE NILU IBADAN

UTC
DEPARTMENT STORE
SERVES
YOU
WELL

ELETI OFE
A-NJU-WON KO SE WI L'EJO

6th & 7th BOOKS OF MOSES
LEDE YORUBA
15/-
ALAPENE NI SABMI OSHODE COMMERCIAL SERVICE
... ROAD IBADAN

VOL. X No. 566. ELETI - OFE LAGOS, SATURDAY, APRIL 5, 1958. KOBO MEJI (2d)

## Oku Adelabu D'oro O Gbode Ibadan Di Jawe Bori

Irchin ko to afojuba niti rogbodiyan to be sile nilu Ibadan lori oku Alhaji Adegoke Adelabu. Bi o ba fe wo ilu Ibadan tabi o fe rekoja nibe, o ni lati ja ewe tutu dani; beni awon Onimoto ni lati ja ewe tutu fi bori moto won ki o to koja ninu Ibadan, bi beko orun alakeji ni oluware alo yen.

Awon obinrin ti o nta'ja ni Molete to sa asala fun emi won lojo ti nwon ngbe oku Adelabu bo lati ona Ijebu koiti pada wo'lu di bi a ti nkowe yi.

Ijoba ti se ofin Isede, ko si eniti o le jade lehin agogo meje ale di owuro ojo keji, nigbati oro di pe—ntuka, oko ko duro wo iyawo re loju. Ilu Ibadan pa roro, kosi Asamu, kosi Awe ki a ma sese tun so ti Wasi mo.

Ibadan di jawe bori.

LAGOS EXECUTIVE DEVELOPMENT BOARD
ITIRE ROAD ESTATE
SURULERE
FREE HOLD HOUSES FOR SALE
IF YOU EARN OVER £500 p.a. and you wish to
OWN A HOUSE OF YOUR OWN
COME AND INSPECT THESE HOUSES
SATURDAY, APRIL 5. TODAY
FREE TRANSPORT From
L. E. D. B. INFORMATION OFFICE
BROAD STREET LAGOS
(OPPOSITE THE DAILY TIMES BOOKSHOP)
AT 4.30 P. M. TO THE SITE
PRICES £1120 — £1670
REASONABLE LOAN TERMS ARRANGED

## Ijebu Di Ota Ibadan

Latete-kose awon eya Ijebu da si meji. Awon ti Ijebu Ode nse ti Ijaiye awon ti Ijebu Remo nse ti Ibadan. Ni·ba gbogbo ni awon ti Ijebu Ode ma ngbe sumomi lo si oko awon ara Ibadan ati si awon ileto won opo enia ni nwon nko li eru lo si Ijebu. Nigbati eyiyi npoaju awon Ibadan mu eru die ati ade oba meta lati fi tu awon Ijebu ninu. Awujale oba Ijebu Ode gba gbogbo awon ebun na o si le awon ojise pada, lati gba yi lo ni Balogun Ogunmola ti kan awon Ijebu sinu.

Lehin ti nwon fo ile Ijaiye tan Balogun Ogunmola bere si wa ona lati gba esan ohun ti awon Ijebu se fun u, Sugbon ko ri bi ati se ko ye so aibikibi pe lojo kan on yio raye gbesan lara Ijebu.

## Eni Nla L'o Nse'un Nla



Iku Alhaji Adegoke Adelabu s'ode kanrin nilu Ibadan. B'o gbawe ase, o ko gbodo jade lehin agogo meje ale di owuro ojo keji, asa awon alawo opa lo nkorin bayi wipe:-

B'olode gbode, A milo, b'olode gbode, A milo.

ARO—Esin kekere, esin tobi?
IDAHUN—Ototo ena ni yio se onigbowo esin.

Lagos Race Club
EASTER MEETING 1958
Saturdays March 29, April 5 Monday, April 7
Saturdays April 12 and 19, 1958.
Racing Starts at 2.30 p.m. each day of the Meeting
DECLARATION
To be made at the Secretary's Office between the hours of 5 and 6 p.m on Fridays, March 28, April 4 Sunday, 6, Fridays April 11 and 18, 1958.
ADMISSION TICKETS (ADVANCE PURCHASE)
ADMISSION TICKETS for the Meeting can be purchased in Advance at the Secretary's Office in the Paddock between the hours of 5 and 6 p.m on the day preceding each day of the Meeting
ADISSION 7/6 per day including Entertainment Tax.
CHILDREN
No Children under the age of 14 years will be permitted to enter the Members Enclosure.
AUCTION SWEEP
There will be an Auction Sweep at the Members Enclosure on the day preceding each day's Race Meeting, commencing from 6.30 p.m.

# Ha! Iku To Nfole Adun

Agn se wa pupo aigbati a gbo ojo iku omo ore wa, Abudu Ganiyu Ayinla Hussain, ti ise omo bibi inu Ogbeni Yusufu. A. Hussain (alias Alaga) ni 19, Agarawu Street, ni ojo Saturday, ti ise ojo keji-lelogun osu March, 1958.

Ise atun-moto-se ni omo na nko (Apprentice Mechanic) labe Oga re Ogbeni Muritala Aka, (Mechanic master) ni Omidun Street, ni Eko. Abudu Ganiyu je omo jeje abiwa pele, ti o ni ojuti fun enikeni, o fi ile aiye sile nigbati o d'agba di omo odun mokandinlogun (19 years).

Afi eyi kewo ki Baba ati Iya re ati eni pataki Madam Ayiratu Ayinke, eniti o to omo na lati kekere titi ti ofi sun orun ikehin, ki Oluwa Alaanujulo tu won ninu, ki o fi ori jin omo na, ki o gbe si afefe rere-emin.

A dupe lowo awon olubakedun wa fun ikanu ofo iku omo rere na nile l'oko ati awon egbe Ansaru-Deen ati awon Al-sal-tu. A dupe l'owo ebi, ore aladugbo ati awon omo ikose Mechanic elegbe re. Oluwa ko tu gbogbo won ninu o. Lati odo Olorun ni a ti wa o si daju pe odo Re ni ao pada si. Ogo ni fun O. Oluwa IRE ni awa yio ma sin titi ojo aiye wa.

# Ilu Ti Orisa Po Nile Yoruba

Orisa po jojo nile Yoruba awon ilu ti a daruko nwonyi ni atile ri awon orisa pupo bi Esie, Oshogbo Ila Orogun Ikirun Iragbiji Ekan Imesi Oloja Oke, Okuku, Ikare Ife Ife Oye Abeokuta Remo ati ni ile Ekiti ati apa ile Benin.

No. 73/S.2/Vol.IX/654.

## Ministry Of Lands And Labour, Western Region Town Planning Division

VACANCY FOR TECHNICAL ASSISTANTS.

Applications are invited for vacant posts of Technical Assistants in the Town Planning Division of the Ministry of Lands and Labour Western Region.

Scale of Salary - Scale F. 1,2,3. £114—276.

For further particulars and method of Application please see Western Region of Nigeria Gazette No. 16 Vol. 7 Notice No. 279 of 20th March, 1958.

Closing Date: 5/4/58.

# Bi Rogbodiyan Ilu Ibadan Tise Bere

A gbo irohin wipe rogbodiyan na bere ni igbati awon ti o lo gbe oku Alhaji Adegoke Adelabu de Oke Mojete, ti awon si ngbe oku na lo si Oke Oluokun, nibiti ile Ologbe na wa ni jamba ipanla na gbe sele.

Opo awon oku lo subu sinu igbo, ti a ko mo oruko won, ni Oden, Omi, Arulogun; Oni kede

(Wo yoku loju ewe keje


Igbadun wa ninu

Oti Heineken's




Agbara Pelu orun didun lo so

Oti Heineken's

di Olokiki julo ninu gbogbo oti agbaiye

## Ase Yori Ise W.H.O.

BRAZZAVILLE. Kakiri nibi gbogbo nilẹ Afrika ni a ṣe akiyesi wipe arun gbogbo ndisku. Nisisiyi arun Ponju-ponju ti kaṣe kuro nighogbo ilẹ wa, adupẹ gidigidi fun iṣẹ ribi-ribi ti awọn Onibupa-bupa ti ṣe. Ibiti arun na tun ku si ni apa ọna Oko Ẹgan.

Bakanna ni arun Sọpọnna tun okaṣẹ a ko tun gburo iṣẹ buruku rẹ mọ. Arun Masun-masun ko tun wọpọ mọ. Arun Lọrun-iọrun ti o mamba awọn ẹranko ja ti o si nran awọn enia ko wọpọ mọ.

Awọn ẹgbẹ W.H O: sọ pe asiko iru igba ajakale arun ti 1918 ko ni si mọ lagbara Ọlọrun. Adupe fun orisi-risi awọn egbogi ti a ṣeṣe ni lọwọ nisisiyi. Awọn ẹgbe yi nigboiya lati sọ wipe iṣe wọn ya ori gedegbe nilẹ Afrika.

## Gbohun—Gbohun

Onigbo-gbagbo te idi mole, o ki gbe bayi pe, iwo Tanu-u? Gbohun-gbohun si dahun pe Tanu-u.


*Gbogbo awọn ẹbi ni i ma a mu*

**OVALTINE**

nitoripe Ovaltine jẹ onjẹ mimu pataki fun ilera, agbara ati okun-inu. Eyi ti nwọn fi ẹyin, irugbin ati wara ṣe ni ọna ọgbọn-ẹrọ, pelu awọn nkan to nmu enia lagbara-Ovaltine jẹ onjẹ ti o pe, ti o si nfun ọmọde ati agba ni okun bakanna. O nmu awọn ọmọ-ọwọ ati awọn ọmọde dagba pẹlu agbara ati okun, o nfun awọn agbalagba ọkunrin ati obirin ni agbara titun ati okun-inu; a si ma jẹki enia sun pelu igbadun, gbogbo ebi ni o nfun ni igbadun ilera ati inu didun.



# OVALTINE

ONJE MIMU PATAKI NI



*Jeki awọn ebi re ma a mu OVALTINE ni akoko onje ati nigbati nwọn ba fe lo sun.*




## Ofin Fun Fere Moto

Awọn Ọlọpa tun ṣe iranti fun gbogbo ilu Eko wipe awọn ko gbọdọ fun fere moto gẹgẹbi o ti wu wọn kakiri ilu Eko, nitoripe awọn aye miran wa ti fere ko gbọdọ dun rara.

(1) Awọn aye ibiti a ko gbọdọ gbọ didun fere moto : Ni ọdan, Kings College, Meloney Street Lawson Street Round about ni ọdan ni gbogbo ọjọ.

(2) A ko gbọdọ gbọ didun fere moto nigboro ilu Eko lehin agogo mọkanla oru si agogo mefa owurọ.

(3) Ati ni gbangba ita Tinubu a ko gbọdọ gbọ iro fere ni gbogbo ọjọ.

**E Ma Ka Iwe Iro-hin Eleti-Ofe Ki E Si Ma Polowo Oja Yin Sinu Re.**

# ELETIỌFE

A-NJU-WỌN KO SE WI L'EJỌ

EDITORIAL OFFICE & WORKS    CABLES & TELEGRAM

28, Kosoko Street, Lagos    "ELETI - OFE LAGOS"

P. O. Box 467    Phone 23370

VOL. X. NO. 566, LAGOS, SATURDAY APRIL 5, 1958.


## Iwa Janduku Ko Dara

Gbogbo irohin rogbodiyan ti o nde etigbọ wa lati ilu Ibadan lati ọjọ ti Alhaji Gbadamọsi Adegoke Adelabu ti pade jamba Moto to fori sọ arawọn ni Opopo Oderemọ l'ọna ilu Shagamu ti ọlọjọ ti de ba Alhaji na ni awọn janduku enia ko ti jẹ ki ilu Ibadan r'oju r'aye mọ lati ṣe eto ohun rere fun anfani ilu.

Kosi enia ẹlemi gẹgẹbi ti Alhaji Adelabu ti jinni-jinni iku rẹ ko mu l'ọkan, tabi ti iku Alhaji na ko dun nitoripe gbogbo enia l'o mọ Alhaji Adelabu ni ẹni nla ati enia pataki ti o to mu opo ilu dani, ṣugbọn ki a wa sọ wipe ayafi ki a ma huwa jagidi-jagan ni ohun ti a le fi kẹdun iku rẹ, asan patapata ni, nitoripe bi ẹgbẹrun enia pada rọrun alakeji, ako le ri Alhaji Adegoke Adelabu laiye mọ.

Nitorina, afi wosika wa yi ke si awọn enia wa ni ilu Ibadan wipe iwa janduku ti yio ma da ilu ru ko sunwọn, ko si le fa ohun rere kan ba wa ni orile-ede. E jẹki a fi adura torọ idariji ẹṣẹ fun Alhaji wa to rekọja, ki Ọlọrun Olodunmare jẹki ipẹhinda rẹ jẹ rere fun ipinlẹ Iwọ-Orun ati gbogbo Nigeria.

E fiyedenu, ẹ ṣe suru.

## Owe Yoruba

Ọkanṣoṣo araba ko nṣẹgbẹ ẹgbaa Ọṣuṣua ọmọ kan to yanju sanju ẹgbẹrun ọmọ lasan lọ.


## Imoran Fun Enyin Abiyamo

Enyin abiyamọ ẹ wa ra ỌMỌRẸLA o dara pupọ fun awọn ọmọde.

Ama jẹ ki ọmode ri orun sun daradara o dara fun otutu, iko ati oriṣiriṣi arun miran ti o ma mba ọmọde ja ni asiko ehin. Ọpọlọpọ abiyamọ lo ti lo egbogi yi fun ọmọ wọn ti wọn si sọ wipe o dara pupọ fun awọn ọmọde

ỌMỌRẸLA BABY MIXTURE

(Ṣile Meji Abọ 2/6d Fun Igo Kan)

O wa Lọdọ

COMMERCIAL MEDICINE STORES

(Qualified Chemists)

10, VICTORIA STREET, LAGOS.

Let's have MUSIC! HEAR THE LATEST HIT NUMBERS



*Read this list of popular titles*

HMV YELLOW & RED DOG

J2 6098 - Kelegbe Megbe/Odun Titun Owo Titun

,, 6099 - Agba Olorin/Busura Baba Osa

,, 6100 - Yawa Yasu/Ọmọlere Aiye Jimo Ojindo

&

his (Sakara) Band

OBTAINABLE FROM:-

1. Y A Bilessanmi - 87 Victoria St, Lagos
2. Animawu Stores - 24 ,, ,, ,,
3. Salawu Aremu - 73 ,, ,, ,,

HMV BLUE DOG

J2A 100- Shogbola/Oluwa Gbawa Lowo Iku Ojiji

,, 101 Bakare Alake/Ejire Baba Taju

,, 102 Raimi Oga Ota/Wahabi Baba Fasila

S. Aka & his (Sakara) Band

OBTAINABLE FROM:-

Omo-ori-Owo Stores

Lagos/Abeokuta

*Sold by all the best stores*

"HIS MASTER'S VOICE" *Yellow Label* RECORDS

HIS MASTER'S VOICE

Distributed by THE UNITED AFRICA COMPANY OF NIGERIA LIMITED

# Kilo Nfa Ogun Wa?

EKO. Ọmọdekunrin, kan ti o sẹṣẹ de lati ile ẹkọ ba iya rẹ nibiti o nse onje lọwọ o bere lọwọ iya rẹ wipe, Baba mi ha ba?

Iya - kilose ti o fi mbere baba rẹ se ko si nkọkan?

Akẹkọ - Ha! beni, k o si kinikan mo nfe bere ọrọ kan lọwọ rẹ ni

Iya - Bi o ba jẹ be lọ wo Baba rẹ ninu Palọ ọmọ na si kọja lọ si Palọ o ba baba rẹ nibiti o gbe nka iwe o dọbalẹ oki i tan o wipe

Akẹkọ - Ha Ngbọ! baba mi bawo ni ogun ti nṣe mbẹrẹ?

Baba - Ha! ọmọ mi; nkan pataki ti o tobi ni ọrọ ti o bere yi ngo si fi ye ọ. Nisisiyi ki a sọ wipe ilu Eko ati Ibadan mba ara won ja.

Iya - Ẹniti o fi eti leko lati gbọ ọrọ ti ọmọ akẹkọ na yio ba baba rẹ sọ dahun lẹsẹkanna wipe, Rara! ilu Eko ko le ba Ibadan ja, nitori kini Eko yio se ba Ibadan ja?

Baba - Howu! obinrin y i mo ti mọ kẹ, mo kan fi nsọrọ lasan ni gẹgẹbi apẹrẹ.

Iya - Rara! eyini ko sunwọn kẹ, ikọkuko ni eyi ti o nkọ ọmọ yen, njẹ iwọ jẹ sọ wipe ki ilu Ilesha wọya ija pẹlu Enugu. Ni baba ba gba ina jẹ :-

(Wo iyoku loju ewe keje)

**Kere o!**

Ati ni origirigi ogun German to sẹṣẹ de, fun oiruru aisan ọkunrin obinrin. Tete wa ra tirẹ s'o to tan.

**J. A. AJAO BROTHERS**

MEDICINE STORES
7, Egerton Road, Lagos.

No. 73/S.2/VOL.IX/657

# The Armorial Bearings Of Western Nigeria




It is notified for general information that the above design for the Armorial Bearings of Western Nigeria has been approved by Her Majesty the Queen and that the use of this design will come into effect immadiately.

The symbolic significance of the design is as follows:-

The two elephants symbolise strength, service and prosperity.

The two symbols which embody the spirit and purpose of the Western Region are the Ada or Chiefs' sword, which is the symbol of the Obas, and the Mace which is the symbol of a parliamentary form of Government and the power of common people as expressed by their elected representatives.

Below the Regional symbols comes the Federal symbol of the Star of David in which is enclosed the Crown of England.

The cocoa tree and the two crossed logs of wood signify the dependence of the Region on, and its respect for, agriculture and the natural resources of the land. The cocoa tree is in the main the symbol of the Yoruba part of the Region, while the two crossed logs of wood denote the timber and the rubber trade of Midwest area.

The final figure is that of the heraldic lion which symbolises not only nobility but the Region's connection with the British Crown.

The motto "Liberty and Service" was chosen for its simplicity and dignity.

## Minister Ile Hausa



Eniti e nwo ninu aworan yi ni okan ninu awon Minister ile Oke Oya eniti oruko re nje Malam Tureta. Imura ti ara awon Hausa ti o je pataki ni eyiti o wa lara re yi.

Nigbamiran awon omo olowo tabi awon omoba a ma mura be pelu. Sugbon nigba atijo imura awon Filani ninu wiwe lawani won a ma fi ijoye oba ati Olowo han. Ilaju, si ti goke nisisiyi bi awon ara Oke-Oya ba mura enia ko le mo Hausa yato si ilumiran.

## Alufa Alaramimo Wo Ina Lorun

Alufa kan mbe nigba aiye ijoun ti nwon pe ni alaramimo, o ko ile re si egbe Mosalasi tobe ti o je pe bi o ba ti jade kuro ninu ile re, inu mosalasi ni yio ko si, ko si ni ibi meji ti o nlo. Ko njade ni gbogbo ojo aiye re mo ko si nje nkan elemi, Olu-Okiti ni eran obe re. Tesuba ko ja kuro lowo re nijokan, Obinrin meji ni iyawo re eleha si ni gbogbo won.

Latigba ti Alufa na ti di eni ogbon odun, ni ko fi oju ri orun mo, Ohunkohun ti enia ba walo sodo re, bi o ba ti ju tesuba re sinu omi fun oluware mu, ohun rere ti eni na nfe yio ri i.

Opolopo enia npe ni Woli. Sugbon Alufa na ni iwa kan ti o nhu si gbogbo enia iwa na ni gberaga. Laifa oro gun lojo kan Alufa yi salaisi.

Nigbati o ku awon Molaika lo gbe oku re lo si orun. Olodumare ni o seun kabo iwo omo odo rere iwo se olotito ninu ohun kekere yi bo sinu ayo Oluwa re. Nigbati Alufa yi gbo be tan ohun ti o jade lenu re ni pe "Ayafi be".

Olodumare dahun pe, Ayafi be bi ti ewo? Ki a ha so wipe iwo ko dese ri ni bi? Emu ese osi re wa sori iwon ni nwon ba ko gbogbo kokoro ti Alufa na ti tepa nigbati o nti ile re bo si inu Mosalasi, sibe-sibe ese osi si tewon. Bori awon baba wa npowe wipe "Igberaga lo nsiwaju iparun". Ko si eniti so bi lati inu obinrin ti ko ni da ese ni won ba ju alufa na sinu ina.




CARSON PAINTS AND VARNISHES



SOLE AGENTS:-
IKORODU TRADING COMPANY
20 & 28, BALOGUN STREET, LAGOS

## Kilo Nfa Ogun Wa?

(O bere loju ewe karun)

**Baba** - Mase ba mi soro palapala o jare emi ha nse omode ti ko mo ohun ti o nso ni, tabi iwo rope nse ni mo si nje ibelu? Mo nsoro fun o pe nse mo fi sapare fun o mo iyen ha le di otito pe ki ilu Eko woya ija pelu Ibadan ndan? Lo soro re o obinrin yi.

**Iya** - Lati gbo lenu re wipe Eko ati Ibadan woya ija ko bo si kati-kati ni eyi ti o nso yen ikokuko lo fi nko omo mi yen. Nibati o ti mo pe Ope ni, emi nse iwo ke ewe si je akuko bawo ni iwo yio ti se ma ko omo mi simi Nigbati omo akeko na nwoye ibiti oro na ngba lo, o wipe:-

**Akeko** - Baba mi eyi ni to, mo ti ri idahun ohun ti mo fe mo ti ri idahun ohun ti mo fe mo ti ri mo aisisiyi gegebi ogun ti se mbere ni gbogbo re ba se wesi bi obe panu.

## Bi Rogbodiyan Ilu Ibadan Tise Bere

(O bere lojo ewe keji)

Irepodun Apadi ati ni Oyedeji.

Ni abule Irepodun awon ti nwon yinbon pa ni Agbe kan ti o nje Latunji Raji. Ni aba Apadi awon sa okunrin arugbo kan ni ada pa.

Ni Omi awon okunrin agbe meji ni nwon pa Bello Aiki ati Suara Ogikede. Nigbore ilu Ibadan gbogbo eniti ke ba ja ewe tutu le ori mo wipe orun nj on nlo ni.

Awon enia ti lati tijokun sobu won pelu tulasi awon ania so wipe enikeni ti o ba se ewe tutu le ori Adelabu ko ni pa oluware nitoripe yio mo pe awon enia ti on ni ati wipe awon gbogbo pe eniti o ba se ewe tutu le ori Alijannu ti yio sokale wa ba awon to pa Adelabu ko ni fowo kan won ati pe lojo Saturday to koja lo lohun ni Alijannu na ti sokale. A si tun gbo pe awon onihoriho enia merinla ni Olopa ramu.

## Akiyesi Pataki

A fi eyi kede fun gbogbo enyin Asoju Iwe Irohin wa nile Yoruba, l'oke Oya, nile Ibo, l'oke Okun ati nilu Oyinbo wipe enikeni ti ko ba fi owo wa ranse ki osu to pari ao ko oruko re fun Loya Eleti-Ofe, ao ba se ejo ao si gba owo irin ese lowo re.

OLOTU.




## Ogun Aran (Ejo Inu)

Aradan Worm Expeller je ogun aran pataki fun omode ati agba okunrin ati obinrin. Ra igo kan lati ya gbogbo awon aran buburu ti o nba o ja ninu danu. Bi o ti npa aran, beni o npa eyin won. Wa ra tire ki o to tan. Igo kan je 2/6d. Owo-Oko si je 1/-.

THE EGBA TRADING ARADAN STORES,
18, Denton Bridge Street,
P.O. Box 2, Ebute Metta.





Awon gbajumo enia gba wipe gegebi mo ti je oga ako ile, mo mo nkan ti awon enia fe, mo si le so wipe Oti Star ni enikeni feran ju.

O da mi loju, ko si eniti o le m'oju kuro nlan adun Oti Star, ndara to be ge, o si lagbara pelu. Tabi iwo yio tun fe si i?

# STAR



OTI STAR

l'o je eyiti odara ju! Beni Sammy Sparkle wi.



Awon ohun elo to darajulo ni afije. Eso o ka barley to l'oran daradara ni a fi se Oti Star. awon enia ti o loye lori pupo l'o nsise Oti Star, omo, o si ni awo to yayi.

Oti Star npa orungbe; adun re ko si lagbe.

## Mose Mba Olorun Soro

Ọlọrun fi iku bẹ awọn ọmọ Israeli wo lailẹkì Mose mọ rara nipa rẹ. Nigbati iku na de, rẹ lo npa awọn ọmọ Israẹli nigba-nigba. Iku na pọ tobẹ ge ti awọn ọmọ Israeli bẹrẹ si fa Mose ṣihin sọhun wipe ki o ba awọn bẹ Ọlọrun rẹ ki o le dawọ iku yi duro.

Mose gun ori oke lọ o bẹrẹ si bẹ Ọlorun pe ki o jọwọ dawọ iku yi duro. Ọlọrun kọ ko dahun. Mose wa pe awọn eya Israeli jọ, o bere tani ṣẹ, ẹnikan ko le dahun pe on lo ṣẹ. Mose ni ki awọn dibo.

Fun iwọn ọdidi ọjọ meji ti awọn ndibo ibo na ko mu ẹnikan. Nigbati o di ọjọ kẹsan ni ibo mu ọkunrin kan ti o ṣe binu si Israeli o si dahun pe bẹni.

Nigbana ni Mose bẹre si ba Ọorun sọrọ pe Haba! Ọlọrun nitori ẹṣẹ ẹnikanṣoṣo ni o ti ṣe pa ẹgbẹrun ọna ẹgberun ninu ọmọ Israeli bayi? ha! o maṣe o.

Ọlọrun kọ si Mose wipe ki o gun ori oke wa. Nigbati o de ori Oke o joko o si sun. Oju orun lo wa nigbati ijalọ kan buje. Mose taji lo lu orun o si ri gbogbo ilẹ ibẹ ti o kun fun ijalọ.

Inu bi Mose o ja ẹkigi, o bẹrẹ si lu wọn p nibiti o gbe nṣe eyi lọwọ ni Ọlọrun kọ si Mose wipe Mose! Mose! kini eyiti o nṣe yi? Mose si dahun pe Ha! Oluwa Ijalọ kan jo bumi je nko si mọ pe awọn tilẹ pọ toyi.

Nigbana ni Ọlọrun dahun pe, Haba? Iwọ Mose mo ṣebi Ijalọ kan ṣoṣo lo bu ọ jẹ ese ti o fi pa ẹgbẹgbẹje ọna ẹgbaji ninu awọn kokoro na.

Nigbana ni Mose sọ pe; bi on ko ba pa wọn bẹ, awọn yoku yio wa bu on je. Ọlọrun dahun o ni ẹhẹn! bi o ti ri lara mi nuni ti mo fi pa ẹgbẹgbẹrun ọna ẹgberun ninu awọn ọmọ Israel nitori ẹṣẹ ẹnikan.

Mo paṣẹ fun wọn pe ninu ogun ti awọn nlọ ẹnikẹni ko gbọdọ mu ohun kan pada wa sile, ṣugbọn ọkunrin yi lọ gbe agbada ẹtu pamọ o si mu wa sinu agọ.

Eyiyi lo di irira si mi, ti mo ṣe si wọn gẹgẹbi iwọ na ti ṣe si awọn Ijalọ.

## Nigerian Railway Corporation

With effect from April 1st 1958, Kafanchan and Jos stations and all intermediate stations hitherto under the Control of the Railway District Superintendent, Saria will come under the control of the Railway District Suprintendent, Enugu. All traffic enquiries relating to this section (Rates and Fares, running of trains etc) should be addressed to the District Suprintendent, Nigerian Railway Corporation, Enugu.

R. B. EMERSON
GENERAL MANAGER



## AGRICULTURE

In the past five years the Western Regional Government has achieved notable successes in its efforts to aid farmers in increasing cocoa production and other crops on which the Region's wealth depends, and to control cocoa diseases.

Efforts have been made to solve the farmers' daily problems. Improved cocoa and oil-palm seedlings have been distributed and encouragement given to citrus and pine-apple planting.

Government intends to develop a cattle industry and a foundation herd of suitable cattle has been built up. In addition improved poultry breeds have been introduced.

Finally the Forestry Department has continued to preserve and enrich the forests on which exports and internal supply depend.

Issued by the Western Nigeria Information Services

Printed & Published by The Union Printing and Publishing Company 28, Kosoko Street P.O. Box 547 Lagos Phone 20370